*Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àinípẹ̀kun. Àmín.*

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

### Kíló kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ tí o ti lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!


*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

**DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL**
*~ À ń tan Ìhìnrere Káárí Aiyé*

**www.divineliterature.org**
**www.doveletters.org**

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023




# Ìwé Ìwọlé tí ó Wúlò

## *Kíni ò ń Gbẹ́kẹ̀lé láti Rí Ọ̀run Wọ̀?*

Àṣìṣe tí ó tóbi jùlọ tí o lè ṣe ní ìgbésí aiyé rẹ ni, kí o kọ̀ láti gba Ẹ̀bùn Ìgbàlà Ọ̀fẹ́ tí Ọlọ́run fún gbogbo ẹ̀dá nípasẹ̀ Jésù Krístì; kí o wá pinnu láti ṣe àwọn iṣẹ́ rere dipo gbígba Ẹ̀bùn náà, láti ní ìtẹ́wọ́gbà Rẹ̀. Kò sí ohun tí o lè ṣe láti dun Ọlọ́run nínú, kí o sì rí Ọ̀run wọ̀, tí ìwọ kò bá jọ̀wọ́ ara rẹ fún Jésù Krístì. Lílọ sí ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstíẹ́nì, ríran àwọn táláká lọ́wọ́, ṣìṣe àtìlẹ́yìn àwọn ẹgbẹ́ alàáánú; pàápàá, kí o máa gbìyànjú láti jẹ́ ènìyàn rere ní àwùjọ dára púpọ̀, àmọ́ àwọn nǹkan wọ̀nyí

*Olùgbàlà mi, mo sì pè é láti jọba nínú ọkàn mi láti òní lọ. Mo dúpẹ́ lọ́wọ́ Rẹ, Jésù Krístì, tí O kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi kí n lè rí ìdáríjì gbà, kí n sì lè ní iyè àinípẹ̀kun. Àmín.*

Tí o bá gba àdúrà yìí látọkànwá, a bá ọ yọ̀, nítorí o ti di ọmọ Ọlọ́run báyìí (Jòhánù 1:12-13).

Kíló kàn lẹ́yìn Ìgbàlà?

Ó ṣe pàtàkì pé kí o máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́ lẹ́yìn tí o bá ti ní ìgbàlà. Wá Bíbélì kan, kí o bẹ̀rẹ̀ sí kàá lójoojúmọ́. Gbogbo ohun tí o ní láti mọ̀ nípa Ọlọ́run, àwọn èro Rẹ̀ sí ọ, àti bí o ṣe lè gbé ìgbésí aiyé tí ó wù ú wà níbẹ̀. Wá ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstẹ́nì kan ní àdúgbò rẹ tí o ti lè gba ẹ̀kọ́ tí ó múnádóko láti inú Bíbélì. Lọ sí ibẹ̀ lẹ́sẹ̀kẹsẹ̀, kí o sì gbèrò láti máa lọ déédé. O lè kàn sí wa nípa ìgbésí aiyé tuntun rẹ nínú Krístì, nípasẹ̀ ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa (Divine Literature International tàbí Dove Letter Zone). Má jáfara láti lo àwọn ohun ìtọ́sọ́nà mìíràn níbẹ̀ tí yóò wúlò fún ọ, pẹ̀lú. Káàbọ̀ sí agboolé Ọlọ́run, olùfẹ́!


*Tí ìwé-pélébé yìí bá wúlò fún ọ, jọ̀wọ́ ṣàjọpín rẹ̀ pẹ̀lú ẹlòmíràn.*

DIVINE LITERATURE INTERNATIONAL
~ À ń tan Ìhìnrere Káárí Aiyé

www.divineliterature.org
www.doveletters.org

Divine Literature International ni òǹkọ̀wé ìwé-pélébé yìí. Wọ́n sì mú u wá fún pínpín ọ̀fẹ́, gẹ́gẹ́ bí Olúwa ṣe ń pèsè. Àwọn Ìwé-pélébé wa kì í ṣe fún títà. Jọ̀wọ́ kàn sí wa nípasẹ̀ àwọn ojúlé wẹ́ẹ̀bù wa tí ẹnikẹ́ni bá ń gbìyànjú láti tà á fún ọ.

©Divine Literature International 2023




Ìwé Ìwọlé tí ó Wúlò

Kíni ò ń Gbẹ́kẹ̀lé láti Rí Ọ̀run Wọ̀?

Àṣìṣe tí ó tóbi jùlọ tí o lè ṣe ní ìgbésí aiyé rẹ ni, kí o kọ̀ láti gba Ẹ̀bùn Ìgbàlà Ọ̀fẹ́ tí Ọlọ́run fún gbogbo ẹ̀dá nípasẹ̀ Jésù Krístì; kí o wá pinnu láti ṣe àwọn iṣẹ́ rere dipo gbígba Ẹ̀bùn náà, láti ní ìtẹ́wọ́gbà Rẹ̀. Kò sí ohun tí o lè ṣe láti dun Ọlọ́run nínú, kí o sì rí Ọ̀run wọ̀, tí ìwọ kò bá jọ̀wọ́ ara rẹ fún Jésù Krístì. Lílọ sí ṣọ́ọ̀ṣì tàbí ibi ìpàdé Krìstíẹ́nì, ríran àwọn táláká lọ́wọ́, ṣìṣe àtìlẹ́yìn àwọn ẹgbẹ́ alàáánú; pàápàá, kí o máa gbìyànjú láti jẹ́ ènìyàn rere ní àwùjọ dára púpọ̀, àmọ́ àwọn nǹkan wọ̀nyí

nìkan kò lè sọ wá di olódodo ní ojú Ọlọ́run. Nípasẹ̀ Ọmọ bíbí Rẹ̀ kan ṣoṣo, Jésù Krístì ni ènìyàn ń di olódodo. Ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú Rẹ̀ ni ọ̀nà kan ṣoṣo tí a lè gbà wọ Ọ̀run (Jòhánù 14:6).

Bíbélì sọ wípé gbogbo àwa ẹ̀dá ènìyàn la jogún Ikú Tẹ̀mí Ádámù (Róòmù 5:12). Nípa bẹ́ẹ̀, olúkúlùkù wa ni a bí ní ènìyàn tí ó ti kú nípa tẹ̀mí. Gbogbo wa ni a bí pẹ̀lú ìtẹ̀sí àdánidá láti dẹ́ṣẹ̀. Àwọn tí wọ́n lépa òdodo nìkan ni wọ́n dára ní ojú Ọlọ́run. Wọ́n wá ìdáríjì ẹ̀ṣẹ̀ nípa gbígba Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà wọn, wọ́n sì ṣe ìpinnu láti máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́.

Krístì san gbèse ẹ̀ṣẹ̀ gbogbo ẹ̀dá nígbà tí Ó kú lórí Àgbélébùú ti Kálfárì. Fún ìdí èyí, gbogbo àwọn ẹ̀ṣẹ̀ tí o ṣẹ̀ ni Ọlọ́run yóò dáríjì tí o bá gbà á gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà rẹ. Lẹ́yìn náà ni ìwọ yóò di ẹni tí ń re Ọ̀run - níwọ̀n ìgbà tí ìwọ bá ti ń ṣe ìfẹ́ Ọlọ́run Bàbá (Mátíù 7:21).

Bí ìwọ bá kọ̀ láti fi aiyé rẹ fún Krístì tí o sì ń bá a lọ láti máa ṣe àwọn iṣẹ́ rere, Ọlọ́run yóò kà ọ́ sí aláìṣòdodo síbẹ̀ náà, nítorípé ìwọ kọ Krístì; àti pé, nípa èyí, o kọ̀ láti gbà kí Ó wẹ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ nù. Ìwọ yóò sì gba ìdájọ́ fún àwọn ẹ̀ṣẹ̀ náà. Kíkọ Ẹ̀bùn Ìgbàlà tí a fi fún ọ nípasẹ̀ Jésù Krístì jẹ́ àìgbọràn àmọ̀ọ́mọ̀ṣe sí Ọlọ́run - ẹ̀ṣẹ̀ nìyẹn fúnraarẹ̀ (Jòhánù 3:36). Àmọ́, Ìròhìn Rere wà! Ọlọ́run kò fẹ́ kí ẹnikẹ́ni dojúkọ ìdájọ́ Rẹ̀ fún ẹ̀ṣẹ̀, kí ó sì ṣègbé nínú adágún iná (Jòhánù 3:16, 2 Pétérù 3:9). Ó ń dúró dè ọ́ láti gba ẹ̀bun Rẹ̀. Ó tún fẹ́ bù kún ẹ lọ́pọ̀lọpọ̀, kí o lè bẹ̀rẹ̀ sí ní ṣe àwọn nǹkan tí Ó dá ọ láti ṣe láiyé. Yí àfiyèsí rẹ kúrò lórí gbogbo ohun mìíràn tí ò ń ṣe pẹ̀lú ìrètí wípé o lè mú inú Ọlọ́run dùn láti wọ Ìjọba Ọ̀run, kí o kọ́kọ́ wá ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú Jésù Krístì ná. Jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún un nísinsìnyí, olùfẹ́. Ọ̀lá lè pẹ́ jù!

## Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì nísinsìnyí?

Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ́ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́.
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.
3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.
4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí:

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n: Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbési aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti*

nìkan kò lè sọ wá di olódodo ní ojú Ọlọ́run. Nípasẹ̀ Ọmọ bíbí Rẹ̀ kan ṣoṣo, Jésù Krístì ni ènìyàn ń di olódodo. Ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú Rẹ̀ ni ọ̀nà kan ṣoṣo tí a lè gbà wọ Ọ̀run (Jòhánù 14:6).

Bíbélì sọ wípé gbogbo àwa ẹ̀dá ènìyàn la jogún Ikú Tẹ̀mí Ádámù (Róòmù 5:12). Nípa bẹ́ẹ̀, olúkúlùkù wa ni a bí ní ènìyàn tí ó ti kú nípa tẹ̀mí. Gbogbo wa ni a bí pẹ̀lú ìtẹ̀sí àdánidá láti dẹ́ṣẹ̀. Àwọn tí wọ́n lépa òdodo nìkan ni wọ́n dára ní ojú Ọlọ́run. Wọ́n wá ìdáríjì ẹ̀ṣẹ̀ nípa gbígba Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà wọn, wọ́n sì ṣe ìpinnu láti máa gbé ìgbé aiyé ìwà-mímọ́.

Krístì san gbèse ẹ̀ṣẹ̀ gbogbo ẹ̀dá nígbà tí Ó kú lórí Àgbélébùú ti Kálfárì. Fún ìdí èyí, gbogbo àwọn ẹ̀ṣẹ̀ tí o ṣẹ̀ ni Ọlọ́run yóò dáríjì tí o bá gbà á gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti Olùgbàlà rẹ. Lẹ́yìn náà ni ìwọ yóò di ẹni tí ń re Ọ̀run - níwọ̀n ìgbà tí ìwọ bá ti ń ṣe ìfẹ́ Ọlọ́run Bàbá (Mátíù 7:21).

Bí ìwọ bá kọ̀ láti fi aiyé rẹ fún Krístì tí o sì ń bá a lọ láti máa ṣe àwọn iṣẹ́ rere, Ọlọ́run yóò kà ọ́ sí aláìṣòdodo síbẹ̀ náà, nítorípé ìwọ kọ Krístì; àti pé, nípa èyí, o kọ̀ láti gbà kí Ó wẹ àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ nù. Ìwọ yóò sì gba ìdájọ́ fún àwọn ẹ̀ṣẹ̀ náà. Kíkọ Ẹ̀bùn Ìgbàlà tí a fi fún ọ nípasẹ̀ Jésù Krístì jẹ́ àìgbọràn àmọ̀ọ́mọ̀ṣe sí Ọlọ́run - ẹ̀ṣẹ̀ nìyẹn fúnraarẹ̀ (Jòhánù 3:36). Àmọ́, Ìròhìn Rere wà! Ọlọ́run kò fẹ́ kí ẹnikẹ́ni dojúkọ ìdájọ́ Rẹ̀ fún ẹ̀ṣẹ̀, kí ó sì ṣègbé nínú adágún iná (Jòhánù 3:16, 2 Pétérù 3:9). Ó ń dúró dè ọ́ láti gba ẹ̀bun Rẹ̀. Ó tún fẹ́ bù kún ẹ lọ́pọ̀lọpọ̀, kí o lè bẹ̀rẹ̀ sí ní ṣe àwọn nǹkan tí Ó dá ọ láti ṣe láiyé. Yí àfiyèsí rẹ kúrò lórí gbogbo ohun mìíràn tí ò ń ṣe pẹ̀lú ìrètí wípé o lè mú inú Ọlọ́run dùn láti wọ Ìjọba Ọ̀run, kí o kọ́kọ́ wá ìbáṣepọ̀ pẹ̀lú Jésù Krístì ná. Jọ̀wọ́ aiyé rẹ fún un nísinsìnyí, olùfẹ́. Ọ̀lá lè pẹ́ jù!

## Báwo ni a ṣe lè gba Jésù Krístì nísinsìnyí?

Bíbélì sọ wípé: Bí ìwọ bá fi ẹnu rẹ jẹ́wọ́ pé Jésù Krístì ni Olúwa, tí ìwọ́ sì gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Ọlọ́run jí i dìde kúrò nínú òkú, ìwọ yóò ní ìgbàlà (Romu 10:9).

1. Gbà pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni ọ́.
2. Ṣe ìpinnu láti yí padà kúrò nínú àwọn ẹ̀ṣẹ̀ rẹ.
3. Gbàgbọ́ nínú ọkàn rẹ pé Jésù Krístì kú fún ẹ̀ṣẹ̀ rẹ lórí àgbélébùú, Ó sì jíǹde kúrò nínú òkú.
4. Lẹ́yìn náà, tẹ orí rẹ ba, kí o gba àdúrà yìí:

*Ọlọ́run Ọ̀wọ́n: Mo jẹ́wọ́ pé ẹlẹ́ṣẹ̀ ni mí. Ẹ jọ̀wọ́, Ẹ dárí ẹ̀ṣẹ̀ mi jì mí. Mo ṣetán báyìí láti kọ ìgbési aiyé ẹ̀ṣẹ̀ mi sílẹ̀. Mo gbàgbọ́ pé Ọmọ Yín, Jésù kú fún ẹ̀ṣẹ̀ mi, Ó jíǹde kúrò nínú òkú, Ó sì wà láàyè. Mo jẹ́wọ́ ọ Jésù Krístì gẹ́gẹ́ bí Olúwa àti*